# Ere bọlu afẹsẹgba Naijiria pẹlu Gold Coast
















## AJIṢAFẸ KO ỌMỌ RẸ JADE

## OYEBODE KO ỌMỌ JADE

## Olori Oloye Onisẹmọ ku

## ILU ỌTAN - AIYEGBAJU D'ẸGBẸ ỌLỌPẸ


THE
New Africa Insurance
Company Limited





# IDAHUN SI IBERE PASTOR FATỌLA


## AWON OGBOLOGBO (SCRAP)

OJE (LEAD)
IDẸ (BRASS)
BABA (COPPER)
AWỌN ALOKU IRIN ẸRỌ MỌTO (RADIATORS)
PAANU AYỌ (ALLUMINIUM)

## JE OWO

Ko wọn wa ta fun

**BUCK (NIGERIA) LTD..**

2. AERODROME ROAD, APAPA.
TELEPHONE
55177.


Lati oju ewe keku nikansoso ni ki iwọ ma sin" (Matteu 4: 10).

"Emi ko da ohunkohun se fun ara mi" (Johannu 8: 28).

"Sugbon niti ojo ati wakati na, ko si enikan ti o mọ ọ, ko si, ki tile ise ise awọn angeli orun, tabi Ọmọ, bikoṣe Baba mi nikansoso.

(Marku 13: 32).

Kinu oro Pastor Fatola, o ni: "Awa Onigbagbo ni a gbe Bibeli Mimọ le lowo lati ma a wasu fun Imale ati awọn keferi nitori okanna ni awọn mejeji."

E jeki a bi alufa yi lere pe, ninu eniti o nsin Ọlọrun kanṣoṣo pere pelu eniti o nsin olorun meji tabi meta tabi merin tabi jù bẹẹ lọ, tani Bibeli pe ni keferi ninu awọn mejeji? Bibeli so bayi: "Iwọ ko gbọdọ li Ọlọrun miran pelu mi. Iwo ko gbodo ya ere kan fun ara re, tabi aworan ohun kan ti mbe loke orun, tabi ohun kan ti mbẹ ni isalẹ ilẹ, tabi ti ohun kan ti mbẹ ninu omi ni isalẹ ilẹ. Iwọ ko gbodo tẹ ori ara rẹ ba fun won, beni iwọ ko gbodo sin won: nitori emi li Oluwa Ọlọrun rẹ. Ọlọrun owu ni mi" (Eksodu 20: 3-5). Ọkanlenirinwo ni awọn olọrun ti keferi nsin ni ilẹ Yoruba; meta ni olọrun ti Kiriyo (Christians) nsin; sugbọn okanṣoso ni Ọlọrun ti Musulumi. Ki eyini duro na.

Sonde (Sunday) ojo isotiṣa awọn ara ilu Romu ni Kiriyo so di ojo isinmi' won dipo ojo Satide (Saturday).

Ọdun Easter ati odun Keresimesi (Christmas) je odun awọn keferi Romu ati ilu miran ni ile awọn alawo funfun sugbon awọn ti so o di odun ajinde ati odun ojo-ibi Jesu.

Jesu ati awọn ọmọ-ẹhin re ko mọ nkankan nipa isin eṣebelebu: Constantine, keferi Oba Romu lo so o di ọrisa ohun akunlebọ fun Kiriyo aiye.

Pastor Fatola tun so fun mi ki nebo, tani keferi ninu iwọ ti o nsin olorun meta pelu Musulumi ti nsin Ọlọrun Aṣo ?

### MUHAMMADU NI OLUGBALA ARAIYE

Iran ọmọ Israeli nikan ni a ran Jesu si. Nitorina isin awọn Juu (Jews) nikan ni isin Jesu. Awọn oro Jesu si jeri si i be:—

"A ko ran mi, bikoṣe si awọn agutan ile Israeli ti o nu," (Matteu 15: 24.).

"Awọn mejila wọnyi ni Jesu ran lọ, o si paṣẹ fun won pe, E maṣe lo si ona awọn keferi, ẹ ma ṣe wọ ilu awọn ara Samaria; sugbon e kuku tọ awọn agutan ile Israeli ti o nu lọ" (Matteu 10: 5-6).

"Mo ni ohun pupọ lati so fun nyin pelu, sugbọn ẹ ko le gba won nisisiyi. Sugbon nigbati on, ani Emi otito ni ba de, yio to nyin si ona otito gbogbo; nitori ki yio so ti ara re; ṣugbon ohunkohun ti o ba gbọ, on ni yio ma a so: yio si so ohun ti mbo fun nyin. On o ma a yin mi logo: nitori yio gba ninu ti emi, yio si ma so o fun nyin." Johanu 16 12-14).

"Nitorina emi wi fun nyin pe a o gba Ijọba Olorun lowo nyin, a o si fi fun orilẹede ti yio ma a mu eso re wa". (Matteu 21: 43).

Awọn Kiriyo nṣbonu pe lehin ti Jesu jinde, o pa a l'aṣẹ pe ki nwọn waasu Ihinrere fun gbogbo aiye "O si wi fun wọn pe, E lo si gbogbo aiye, ki ẹ si ma a waasu Ihinrere fun gbogbo eda. (Marku 16: 15). Aliṣe akiyesi oro inu Bibeli won daradara ni nwọn se nso bee, nitoripe kiumo "gbogbo aiye" ti a lo ninu Bibeli ki ise gbogbo orilẹede ni a lo o fun, paapa ninu Majemu Titun, bikoṣe fun ile Siria tabi fun gbogbo iran Juu. Fun apere a ka a ninu iwe Luku bayi pe: "O si se li ojo wọnni, aṣe ti odọ Kesari Augustus jade wa pe, ki a ko oruko gbogbo aiye sinu iwe. (Eyi ni ikosinu-iwe ikini ti a se nigbati Kireniu fi je Bale Siria). Gbogbo awọn enia si lo lati ko oruko re sinu iwe, olukuluku si ilu ara re." (Luku 2: 1-3). Dajudaju "gbogbo aiye" ti oro Bibeli yi wi ko le kan ilu Gẹẹsi tabi ilu Faranse tabi Rosia tabi ilu wa; lalai-aniani ilu won nikan ni nwọn pe ni "gbogbo aiye". Ki eyini duro bee.

Gbogbo awọn alufa Kiriyo pataki pataki ni nwọn gba pe awọn oro inu ẹsẹ ikẹrindilogun lati ese kesan de'le ninu iwe Marku se oro ti awọn enia miran fi kun un ni ife inu won. Dr. E. W. Barnes ti a daruko re lekan tun jeri si i bee ninu iwe re ti a toka si lekan. Bee si ni iwe Marku yi ni Matteu ati Luku wo ti nwọn fi ko iwe tiwon.

Sugbon a ran Muhammadu si gbogbo orile-ede aiye, nitorina ni o se kowe si Heracleus Oba Romu, ati Chosroes, Oba Persia ati awọn oba ilu miran se ki nwon wa gba Islam ti a fi ran on nisẹ nitoripe ase Olorun ni:—

"Awa ko ran o nise (miran) bikoṣe awọn enia (aiye patapata) gẹgẹbi oniroyin-idunnu ati olukilọ, sugbon opolopo awọn enia ko mọ." (Sura 34: 28).

## Bello Oluwamakọ fi Ẹgbe Ajiṣafẹ silẹ

(IDOFIAN)

Ni ojo Aje ti ise ojo kejilelogun osu kewa odun yi ni Mallam Bello Oluwamakọ fi Ẹgbẹ Ajiṣafẹ silẹ, o si on ko se mọ pa a ni "Iwofun nileloruñ" o si bọ sinu Ẹgbe Nina-lowo-koburu.

Awọn ẹgbẹ yi si 'i kidunnu ati ayọ gba Mallam Bello Oluwamako sinu ẹgbe na nitoripe Bello Oluwamakọ jẹ enia pataki ni. o si jẹ eniti o mọ eto larin ẹgbe ti o ba wa. Olorun Olodumare ki o mu ese ẹgbẹ na duro o.


## MERCEDES-BENZ



### THE 5/6 TON LORRY FOR

★ RELIABILITY AND LONG LIFE
★ LOW FUEL CONSUMPTION
★ HIGH PERFORMANCE

WITH A FULLY ORGANISED "AFTER SALES" SERVICE
AT MODERATE CHARGES
SUPERVISED BY EXPERT ENGINEERS FROM THE
MERCEDES WORKSHOPS.

## LEVENTIS MOTORS

DISTRIBUTORS FOR NIGERIA


Printed and Published by the Amalgamated Press (of Nigeria) Ltd. 5/7, Apogbon Street, Lagos (Editorial and Advert. offices) Tele. 20855, 2056.
Fun Owo Irohin Yoruba odun kan:—Eko-ilẹ mejo ati ... mejo (8s. 8d.) Fi ... si Ngeria ati Oke-Okun ... (13s.) Ọdọ E. M. ... Chapel Street, Lagos.